# LATI INU IKÚ SI IYE

**Efesu 2:1-22.**

**ẸKỌ 401 – FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Ore-ọfẹ li a ti fi gbà nyin là nipa igbagbọ́; ati eyini ki iṣe ti ẹnyin tikaranyin: ẹ̀bun Ọlọrun ni"(Efesu 2:8).**

**I Fifi Eniyan nipa ti Ara wé Eniyan nipa ti Ẹmi**

1 Paulu fi ipò ti wọ́n wà nisisiyii wé ti igba atijọ ri, Efesu 2:1-3; 4:18; Kolosse 2:13; 1 Johannu 5:12; Romu 8:2-6.

2 O fi ipasẹ ohun ti a fi gbà wọ́n là, ati eredi ti a fi gbà wọn là hàn, Efesu 2:4-7; Romu 5:6, 8; 6:4, 5.

3 A gbà wọn là nipa oore-ọfẹ a si ṣe ẹ̀da wọn fun iṣẹ rere; Efesu 2:8-10; 1 Kọrinti 3:9; 2 Kọrinti 5:17; 2 Timoteu 1:9.

4 Nipa Ẹjẹ Kristi ni a wó ogiri ikele ti ó wà laaarin lulẹ̀, Efesu 2:11-14; Galatia 3:29; Kolosse 1:20.

5 Ju ati Keferi ni anfaani lati lọ sọdọ Baba nipasẹ Kristi, Efesu 2:15-19; 2 Kọrinti 5:18; Galatia 6:15; Kolosse 1:20-23; 2:14.

6 A gbé gbogbo wa ró lori ipilẹ kan naa a si n dagba soke pọ̀ gẹgẹ bi tẹmpili mimọ́. Efesu 2:20-22; 2 Kọrinti 6:16; Heberu 12:22, 23; 1 Peteru 2:5; Ifihan 21:14.

**ALAYE**

## Oriṣi Ikú Meji

Paulu fi eniyan nipa ti ara wé eniyan nipa ti ẹmi. O fi hàn ohun ti a jẹ́ gẹgẹ bi ẹda wa ati ki ni a jẹ́ nipa oore-ọfẹ. Eniyan jẹ́ ohun mẹta ninu ọ̀kan, eyi ti i ṣe ara, ọkàn ati ẹmi. Ikú ti ara wà ti n sọ ara di oku ikú ti ẹmi si wà ti n sọ ọkàn di oku. Ikú ti igba isisiyii ni yiya ọkàn ati ẹmi nipá kuro ninu ara. Ikú ti ẹmi ni n ya eniyan nipá pẹlu Ọlọrun nigba ti ẹni naa ṣi wà ninu ayé, bi o ba si wà ninu ipò bẹẹ titi lọ, a o da a lẹbi ijiya ayeraye, eyi ti i ṣe ikú keji. Ikú ti Ẹmi jẹ́ abayọrisi didá ẹ̀ṣẹ. Aigbọran Adamu fa ikú ti ara ati ti ẹmi wá si ori gbogbo iran ọmọ-eniyan. Ki Adamu to da ẹ̀ṣẹ kò si ikú. Kristi ni agbara lori ikú ti ara ati ti ẹmi.

Nigba ti a ba n rò nipa ikú ti ara, a n rò nipa ọta ni ti n wọle ti n mu olufẹ wa kan lọ. [Ka 1 Kọrinti 15:26] A maa n fi oju ara ri ikú yii. Ṣugbọn, ikú ayeraye, tabi idalẹbi ọkàn, ni a kò le fi oju ara rí, ṣugbọn Oluwa nikan ni O n ri i ti O si n mọ bi o ti buru tó. O rán Ọmọ Rẹ̀ lati ṣe ọna lati là. "Nitori Ọlọrun fẹ araiye tobẹ̃ gẹ, ti o fi Ọmọ bibi rẹ̀ kanṣoṣo funni, ki ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ́ má bà ṣegbé, ṣugbọn ki o le ni iye ainipẹkun" (Johannu 3:16)..

Jesu wi pe, "Ẹ má fòiya awọn ẹniti ipa ara, ṣugbọn ti nwọn ko le pa ọkàn: ṣugbọn ẹ kuku fòiya ẹniti o le pa ara ati ọkàn run li ọrun apadi" (Matteu 10:28). Oluwa n ṣe akiyesi gbogbo ijiya wa ninu ara, nitori a rii ninu Ọrọ Rẹ̀ pe, "Iyebiye ni ikú awọn ayanfẹ rẹ̀ li oju OLUWA" (Orin Dafidi 116:15). Bi a ba ti tún ọkàn kan bí, ti o si n rin deedee ni oju Oluwa, nigba ti ara rẹ̀ ba kú, ẹmi yoo fò tọ Ọlọrun lọ ti O fi i fun ni, nibẹ ni yoo si maa wà titi lae. Jesu sọ wa di ominira kuro lọwọ ide ẹ̀ṣẹ ati ikú; O si fun wa ni iye ainipẹkun. "Lõtọ, lõtọ ni mo wi fun nyin, Ẹnikẹni ti o ba gbọ́ ọ̀rọ mi, ti o ba si gbà ẹniti o rán mi gbọ́, o ni iye ti kò nipẹkun, on ki yio si wá si idajọ; ṣugbọn o ti ré ikú kọja bọ si iye" (Johannu 5:24).

## Ajinde ti Ara

Nigba ti ara kan ba kú, bi ọkàn rẹ̀ ba ṣe deedee pẹlu Ọlọrun ti o si wa laaye nipa ti ẹmi, oun (ọkàn) yoo tun ni idapọ pẹlu ara naa, nitori pe ajinde ti ara n bẹ. "Nitori ipè yio dún, a o si ji awọn okú dide li aidibajẹ, a ó si pawalara dà. Nitoripe ara idibajẹ yi kò le ṣaigbé aidibajẹ wọ̀, ati ara kikú yi kò le ṣaigbé ara aiku wọ̀. Ṣugbọn nigbati ara idibajẹ yi ba ti gbe aidibajẹ wọ̀, ti ara kikú yi ba si ti gbe aikú wọ̀ bẹ̃ tan, nigbana ni ọ̀rọ ti a kọ yio ṣẹ pe, A gbé ikú mì ni iṣẹgun. Ikú, oró rẹ dà? Isà okú, iṣẹgun rẹ dà?" (1 Kọrinti 15:52-55; Ka Romu 8:19-23 pẹlu).

**Ọgbẹni Ọlọrọ ati Lasaru**

Jesu sọ fun ni nipa ọgbẹni ọlọrọ ati Lasaru. Awọn ọkunrin mejeeji naa kú. Eyi ọgbẹni ọlọrọ ti gbé ninu gbogbo ọ̀ṣọ́ ati ogo ayé yii. Owo iyebiye ni o ná lati ṣe ara rẹ̀ lọṣọ, ṣugbọn kò tilẹ ronu nipa ẹmi rẹ̀. Boya oun naa n sọ, gẹgẹ bi ọ̀pọlọpọ eniyan pe, "Akoko pupọ ṣi wà sibẹ." A sin in ninu ọṣọ ati ogo didan ti ayé yii le fi fun eniyan. Ṣugbọn Ọrọ ni sọ fun ni pe ni ọrun apaadi ni o gbé ojú rẹ̀ soke o si ri Lasaru lokeere ni ookan àya Abrahamu. Ẹmi ti ọkunrin ọlọrọ̀ kò naani rẹ̀ lọ si ọrun apaadi – o si ṣegbe, o ṣegbe titi ayé, o kú nipa ti ẹmi.

Lasaru jẹ́ alaini ṣugbọn o ti mura silẹ lati pade Ọlọrun. Ọkàn rẹ̀ si wà laaye – ó wà laaye titi lae.

**Irú-Ọmọ Abrahamu**

Ọlọrun yan irú-ọmọ Abrahamu lati di orilẹ-ede ninu eyi ti a le bi Ọmọ Rẹ̀ lati mu irapada wá fun ayé ti o ti ṣegbe.

Awọn Ju rò pe awọn nikan ni o ni ẹtọ si Ijọba Ọlọrun. Oluwa pe Paulu, O si yàn án ni Apọsteli, O si fi oye Ihinrere ye e ni ẹkunrẹrẹ, pe ó (Ihinrere) wà fun "Ẹnikẹni ti o ba fẹ." Nipa ikú Jesu Kristi ilẹkun aanu ṣi silẹ gbagada, gbogbo orilẹ-ede Keferi si le wọ inu rẹ̀ bi wọn bá wá Oluwa.

**Awọn Ara Efesu**

Paulu lo akoko diẹ lati waasu Ihinrere ni Efesu, ilu Keferi. Ijọ ti a dá silẹ nibẹ di pataki o di alagbara fun ẹsin Igbagbọ́. Awọn ara Efesu wọnyii ti jinlẹ ninu ibọriṣa, ṣugbọn nigba ti wọn gbọ́ iwaasu Paulu, pupọ ninu wọn gbagbọ́, Ẹmi Ọlọrun si sọ ọkàn wọn di aaye. Wọn ti jẹ́ okú ninu ẹ̀ṣẹ ati irekọja gbogbo, ṣugbọn nisisiyii a sọ wọn di alaaye ninu Kristi Jesu. Ibi titun ti ṣe iyipada igbesi-ayé wọn. Titi di igba ti a fi tun wa bi, ati Ju ati Keferi ni a ti n rin gẹgẹ bi ifẹkufẹ ti ẹran ara. Ṣugbọn nigba ti a gba wa là ifẹ ọkan wa yipada a kò si rin nipa ti ara mọ́ bi ko ṣe nipa ti Ẹmi, a si bẹrẹ si i ṣe awọn ohun ti i ṣe ododo niwaju Ọlọrun.

Ni Efesu ni a kọ́ tẹmpili nla ti Diana si, eyi ti i ṣe ọ̀kan ninu awọn ohun iyanu meje ti ó wà ni ayé. Awọn alagbẹdẹ fadaka fi yiya ère Diana keekeekee ṣe iṣẹ ṣe wọn si n tà wọn. Ọpọlọpọ awọn eniyan Efesu gba Ihinrere gbọ́ to bẹẹ ti òwo awọn alagbẹdẹ fadaka bọ́ sinu ewu bibajẹ. Wọn gbé irukerudo dide si Paulu, oun si ni lati fi ilu naa silẹ.

(Ka Iṣe Awọn Apọsteli 19).

**Aanu**

Titoobi aanu Ọlọrun ti o fi fẹ́ wa nigba ti a jẹ ẹlẹṣẹ ti O si sọ ọkàn wa di aaye nipa Jesu Kristi, ti O si mú Ju ati Keferi joko papọ ninu awọn Ọrun ninu Kristi Jesu. Ihinrere maa n mu irẹpọ wá. Bawo ni ẹni meji ṣe le rin pọ̀ bi kò ṣe pe wọn rẹ́? Irẹpọ wo ni o wà laaarin imọlẹ ati òkunkun? tabi ki ni tẹmpili Ọlọrun ni i ṣe pẹlu oriṣa?

**Igbala nipa Oore-ọfẹ**

"Ki iṣe nipa iṣẹ, ki ẹnikẹni má bã ṣogo" (Efesu 2:9). Oluwa ti ṣe eto igbala nla yii lọna ti yoo fi jẹ́ nipa oore-ọfẹ nikan. Ọmọ eniyan ti gbidanwo fun ọ̀pọlọpọ ọdún ni ọna gbogbo lati le sọ ara rẹ̀ di ominira kuro labẹ agbara ẹ̀ṣẹ, ṣugbọn kò ṣe e ṣe. Nipa Ẹjẹ Jesu, ani nipa Ẹjẹ Rẹ̀ nikan ṣoṣo ni a le fi pa ẹ̀ṣẹ run ninu ọkàn ọmọ-eniyan.

Bi o ba ṣe pe iṣẹ rere le mu wa ri ojurere Ọlọrun ọpọlọpọ ni iba yara kankan lati ṣe e. A ki ba tun maa wá Olugbala kan mọ́. Ọlọrun bu ọla fun iṣẹ Ọmọ Rẹ̀. "Ẹniti o ba ni Ọmọ, on ni iye; ẹniti kò ba si ni Ọmọ Ọlọrun, ko ni iye" (1 Johannu 5:12). Ọlọrun fi lelẹ pe ki iṣẹ rere jẹ́ eso igbesi-aye wa nigba ti a ba yi ọkàn wa pada ti a ba si rekọja lati inu ikú si iye. O jẹ́ iwa ẹda Onigbagbọ́ lati maa ṣiṣẹ ododo. Iṣe rere jẹ́ iwa ti i maa ṣẹlẹ lẹsẹkẹsẹ lati inu ọkàn ti o fẹ́ Ọlọrun, ki i ṣe nnkan ti a n ṣe lati fi wá oju rere Ọlọrun.

Igbala kuro ninu ẹ̀ṣẹ jẹ́ ẹbun Ọlọrun fun araye nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa; nitori bẹẹ kò si ẹnikẹni ti o le ṣogo pe oun san ohunkohun fun igbese irapada rẹ̀.

**Jinna Réré**

A sọ pe awọn Ju "sunmọ tosi" Ọlọrun nitori Ofin, majẹmu ati anfaani ti wọn ni lati wá Ọlọrun nipa irubọ ati ẹjẹ etutu. Awọn Keferi ko ni anfaani wọnyi lati fi sun mọ tosi Ọlọrun, nitori bẹẹ a sọ pe wọn "jina rere."

Bi Ẹjẹ Jesu Kristi ti n ṣàn silẹ lati ori agbelebu igi oró ni, isẹlẹ sẹ̀ ninu ilẹ, o si bú jade ninu ooru gbigbona. Awọn ọrun paapaa ṣokunkun biribiri, apata fọ́, awọn iboji okú si ṣi silẹ. Aṣọ ikele Tẹmpili faya si meji lati oke dé ilẹ. A si sọ fun awọn Keferi lati wọle. "Ẹnyin Keferi, ẹ mã yọ̀. . . . . ẹ si kokiki rẹ̀, ẹnyin eniyan gbogbo." Ju ati Keferi le wá sọdọ Ọlọrun Alaaye nisisiyii nipa ibuwọn Ẹjẹ Jesu Kristi.

A kò tun sọ mọ pe awọn Ju "sunmọ tosi" awọn Keferi si "jina réré", ṣugbọn olukuluku ni anfaani nipa ti Ẹmi si ọdọ Baba.

**Tẹmpili Oluwa**

Ju ati Keferi jumọ ṣe ọmọ ibilẹ ilu Ọrun, gbogbo wọn si jẹ́ ọmọ agboole igbagbẹ́ rẹ̀. Wọn ni ipilẹ kan naa, ati ti awọn Apọsteli ati awọn wolii, Jesu Kristi si ni Pataki Okuta Igun ile, nipasẹ Rẹ̀ ni a si so awọn mejeeji pọ̀ ninu ile kan naa.

A so awọn mejeeji pọ̀ timọtimọ nipa Ẹmi Mimọ́ sinu Tẹmpili nla kan ṣoṣo naa ti Oluwa. A ko i ti i pari iṣẹ kikọ́ ile naa ṣugbọn o n tẹ̀ siwaju lati ọjọ dé ọjọ, ati pe lai pẹ ọjọ, ẹni mimọ́ kan ṣoṣo ti o kù yoo si ti wọle, ogo Oluwa yoo si tàn imọlẹ sinu Tẹmpili naa, awọn eniyan mimọ́ yoo si maa gbé ibẹ̀. A o gbé ikú mi ni iṣẹgun.

**AWỌN IBEERE**

1. Ara ati Ẹmi ha n wa laaye lẹyin ikú bi?
2. Iru ipo wo ni awọn ara Efesu wá ki wọn to gbọ́ Ihinrere?
3. Njẹ iṣẹ rere le gbà wá là? Bi kò ba ṣe bẹẹ, ki ni n mu ni wà ni ojurere pẹlu Ọlọrun?
4. Ki ni mu iyapa wá laaarin Ju ati Keferi?
5. Njẹ ogiri idabu ni ṣi wà sibẹ?
6. Iru ile wo ni a fi awọn eniyan mimọ́ wé?
7. Ori Ipilẹ wo ni a gbé Ihinrere lé?
8. Nigba ti ikú ba de nibo ni ẹmi ati ara n lọ?